Fun mi ni iro nipa ti mo ba ki awọn irun ọran-anyan, ti mo gba awẹ Ramadan, ti mo ṣe ẹtọ ni ẹtọ, ti mo ṣe eewọ ni eewọ

Lati ọdọ Jaabir- ki Ọlọhun yọnu si i-: Dajudaju arakunrin kan beere lọwọ Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, o sọ pe: Fun mi ni iro nipa ti mo ba ki awọn irun ọran-anyan, ti mo gba awẹ Ramadan, ti mo ṣe ẹtọ ni ẹtọ, ti mo ṣe eewọ ni eewọ, ti mi ko le nnkan kan kun lori ìyẹn, njẹ maa wọ alujanna? O sọ pe: “Bẹẹni”, o sọ pe: Mo fi Ọlọhun bura pe mi ko nii le nnkan kan kun lori ìyẹn.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe dajudaju ẹni ti o ba ki awọn irun ọran-anyan maraarun-un ti ko le nnkankan kun ninu awọn nafila, ti o si gba awẹ Ramadan ti ko gba awọn aṣegbọrẹ, ti o ni adisọkan jiję ẹtọ nnkan ẹtọ ti o si ṣe é, ti o ni adisọkan jiję eewọ nnkan eewọ ti o si jina si i, dajudaju yoo wọ alujanna.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/65003